## Research Notes

# Àgbéyẹ̀wò "Digital Nollywood" (Ọ̀rọ̀ láti ẹnu àwọn àgbà òṣèré) àti "Ògbóǹtarìgì"

'Gbenga Adeoba
Program in Comparative Literature
Washington University in St. Louis
adeoba@wustl.edu

Digital Nollywood jẹ́ iṣẹ́ ìwádìí dígítà tí ó bẹ̀rẹ̀ ní 2018 láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn fíìmù ní Nàìjíríà. Ìlànà ìwádìí yìí ń ṣe àmúlò àwọn ohun àfojúrí àti àwọn ìwé àlẹ̀móde tí wọ́n fi ṣe ìpolówó àwọn fíìmù, pàápàá jù lọ ní ikọ̀ fíìmù tí a mọ̀ sí Nollywood. Fún iṣẹ́ Digital Nollywood, a rí àwọn ohun èlò àfojúrí àti ìwé àlẹ̀móde wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bíi iṣẹ́ ọnà tí ó wúlò fún ìṣèwádìí iṣẹ́ ìtàn Nollywood ní ọ̀nà tí ó yàtọ̀. Ní oríṣiríṣi ọ̀nà, iṣẹ́ yìí ń lo àwọn ìwé àlẹ̀móde wọ̀nyí láti ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn àwọn ohun ìkéde tí ó ṣe àmúlò àwọn nǹkan tí ó jẹ́ tiwantiwa. Ní ìtají sí bí àwọn ohun èlò àfojúrí àti ìwé àlẹ̀móde wọ̀nyí ti ṣe ń di àwátì, iṣẹ́ yìí ń ṣe àmúlò àwọn ìtẹ̀síwájú tí ó pemọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ láti wo àwọn ọ̀nà míràn tí a lè gbà se iṣẹ́ ìwádìí ìtàn tàbí se àgbéyẹ̀wò àṣà àti ìṣe ní ilè Africa. Nípasẹ̀ àmúlò ohun àgbéjáde ayélujára, Digital Nollywood ní èrò láti di iṣẹ́ ìwádìí dígítà tí ó ń ṣe ìdásí àti ìtẹ̀pẹpẹ ìwé àlẹ̀móde àwọn fíìmù Nollywood nípasẹ̀ àgbàjọ àwọn ìwé wọ̀nyí ní orí pẹpẹ Omeka.

Fún abala 'Oro lati enu awon agba osere,' afojúsùn iṣẹ́ yìí ni láti ṣe àkójọpọ̀ àti àkọsílẹ̀ àwọn ìtàn àti ọ̀rọ̀ ẹ̀rí láti ẹnu àwọn àgbà òṣèré Yorùbá. Ní ìbámu pẹ̀lú ètò tí à ń tẹ̀lé, a yóò máa ṣe àgbéjáde àwọn iṣẹ́ ìtàn wọ̀nyí bí wọ́n bá ṣe ń tẹ̀ wá lọ́wọ́. A yóò ṣe àgbàwọlé àti àmúlò ìrànlọ́wọ́ tàbí ìdáhùn tí ẹ bá fi ṣọwọ́ sí wa. Fún àwọn ìfọ̀rọ̀wérọ̀ àkọ́kọ́, Rasaq Malik, Oǹkewì, ọmọ bíbí ìlú Nàìjíríà, káàkiri ẹkùn gúúsù-ìwọ̀ oòrùn Nàìjíríà. Ó bá àwọn àgbà òṣèré bíi Bàbá

Lere Paimo àti Alàgbà Musiliu Dasofunjo sọ̀rọ̀ nípa isẹ́ fíìmù Yorùbá ní orílẹ̀ èdè Nàìjíríà.

Ògbóǹtarìgì jẹ́ Iṣẹ́ tí ó jẹyọ lati ara ìrírí wa ní ìgbà tí àrùn COVID-19 gbòde kan. Láti rọ́pò Ikórajọ tí a máa ń se lórí ọ̀rọ̀ àṣà, èyí tí a pè ní Jomitoro, a bẹ̀rẹ̀ sí kó àwọn èèyàn jo ní orí pẹpẹ Zoom fún ìwé kíkà ní èdè Yorùbá. Ní orí pẹpẹ yí, a máa ń ka àwọn ìwé Yorùbá tí ó dáńgájíá, àwọn èèyàn láti àwọn orílè-èdè míràn sì máa ń darapọ̀ mọ àwọn tí ó wà ní orílè-èdè Nàìjíríà. Lára àwọn ìwé tí a ti kà jẹ Eégún Aláré láti ọwọ́ Láwuyì Ògúnníran. Lẹ́yìn tí a parí ìwé yìí, tí àwọn èèyàn sì ń fọ̀rọ̀wérọ̀ lọ́jọ́ náà, ẹnìkan ní ó jọ wípé oǹkọ̀wé náà ti papòdà, kí ẹlòmíràn tó fèsì wípé kò rí bẹ́ẹ̀. Wọ́n ní dáadáa ni Bàbá náà wà. Èyí mú wa bẹ̀rẹ̀ ìwádìí, a sì ríi wípé lóòótọ́ ni Bàbá náà sì wà. A gba ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn sílẹ̀, a sì fún wọn ní àmì ẹ̀yẹ fún ipa ribiribi tí wọ́n kó lórí lítíréṣọ̀ Yorùbá. Kò ju ọ̀sẹ̀ méjì tí a ṣe èyí tán ni wọ́n papòdà.

Láti orí Iṣẹ́ ìgbàsílè ọ̀rọ̀ ẹrí àkókò yìí ni a ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ Ògbóǹtarìgì. A bẹ̀rẹ̀ rẹ̀ láti ṣe àfihàn àti ayẹ́sí àwọn àgbà oǹkọ̀wé èdè Yorùbá tí wọ́n ti mú àgbéga bá èdè àti àwọn àṣà wa, yálà nípa Iṣẹ́ wọn tàbí ní ti ìgbé ayé wọn. Àwọn òpó ìgbéjáde tí a fojú sí sì jẹ́ YouTube àti pẹpẹ Wikipedia. Àwọn àfojúsùn wá nìwọ̀nyí:

- Láti se ayẹ́sí àwọn oǹkọ̀wé àti iṣẹ́ ribiribi wọn lórí bíbu iyì kún èdè àti àṣà Yoruba.
- Láti ṣètò ìwúrí fún àwọn ọ̀dọ́ nípa ìtàn àti iṣẹ́ àwọn àgbà wọ̀nyí. A lérò wípé èyí yíò jẹ ìmísí fún wọn láti rí àwọn ọ̀nà tí wọ́n lè gbà gbé èdè àti àṣà lárugẹ.
- Láti túbọ̀ ṣe àfihàn àwọn oǹkọ̀wé Yorùbá lórí ẹ̀rọ ayélujára, ní ọ̀nà tí a lérò wípé ó lè mù àtúnṣe bá àwọn àfojúdá tí ó ti jẹyọ.

Digital Nollywood ("Ọ̀rọ̀ láti ẹnu àwọn àgbà òṣèré") ati "Ògbóǹtarìgì" jẹ́ Iṣẹ́ meji gbòògì tí ó túbọ̀ ṣe àfihàn àwọn ọ̀nà tí ìmọ̀ ẹ̀rọ àti ìmọ̀ ẹ̀kọ́ dígítà ṣe leè di àmúlò nínú àwọn ọgbọ́n ìṣèwádìí, pàápàá jùlọ ní ti èyí tí ó jẹ mọ́ ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ti èdè àti àṣà Yorùbá pẹ̀lú ìmọ̀ tí ó rọ̀ mọ́ wọn. Àwọn Iṣẹ́ bíi "Yoruba Names" ati "African Language Technology Initiative" àti àwọn iṣẹ́ míràn ti ṣe ìfilọ́lè irú àwọn Iṣẹ́ báyìí. Àmọ́ ní ọ̀nà tí ó yàtọ̀, àwọn Iṣẹ́ tuntun méjèèjì yìí ṣe ìtẹ̀síwájú àti ìfìdímúlẹ̀ àwọn irú Iṣẹ́ bẹ́ẹ̀. Ní ọ̀nà kan, àwọn Iṣẹ́ méjèèjì yí dá lórí ìwádìí ìtàn àti ìgbàsílè ọ̀rọ̀ ẹ̀rí láti ẹnu àwọn tí ó ti gbé tàbí sì ń gbé èdè Yorùbá lárugẹ nípa Iṣẹ́ wọn—yálà gẹ́gẹ́ bíi eléré orí ìtàgé, oǹkọ̀wé, akéwì/oǹkewì, tàbí agbéṣéjáde. Ní ọ̀nà míràn, lábé àwọn àfojúsùn Digital Nollywood, wọ́n ń wádìí ìtàn Nollywood nípasẹ̀ ọgbọ́n ìṣèwádìí tí ó ń se àmúlò àwọn ohun èlò àfojúrí àti ìwé àlẹ̀móde fíìmù tí wọ́n ń gbà jọ fún ìdásí. Lápàapọ̀, Iṣẹ́ méjèèjì yìí ń ronú ọjọ́ iwájú; wọ́n ń ṣe àfihàn ìtẹ̀síwájú èdè Yorùbá. Wọ́n sì ń lọ èrò

ayárabíàṣá, àti àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ tí ó jé mọ́ọ, fún ìrúsókè èdè àti láti buyì fún àwọn Iṣẹ́ tí ó ń gbé èdè àti àṣà Yorùbá láruge.

Ìdáyàtọ̀ àti pàtàkì Iṣẹ́ Digital Nollywood hàn nínú ọ̀nà tí Iṣẹ́ náà ń gbà láti se ìwádìí ìtàn nípa èlò àwọn ohun aláfojúrí àti ìwé àlẹ̀móde. Fún àpẹẹrẹ, àwọn ìwé àlẹ̀móde tí ó fi ojú àwọn òṣèré láti ayé Alárìnjó hàn àti ibi tí wón ti ń ṣeré gbogbo pẹlu àwọn ìwé àlẹ̀móde tí wọ́n ti gbà jọ. Èyí sì wúlò púpọ̀ nítorí wípé ìtàn tí ó je mọ́ sáà yìí ṣe pàtàkì nínú ìtàn fíìmù Yorùbá ní àpapọ̀. Nínú abala "Ọ̀rọ̀ láti ẹnu àwọn òṣèré," ó tọ́ kí a kí àwọn olùwádìí yìí kúuṣẹ́ nítorí irú àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀rí tí wọ́n ń gbà sílè; ó fi hàn wípé wọ́n mọ rírì ìwúlò ìrírí àti ọ̀rọ̀ ẹ̀rí àwọn tí ó jé àgbà lénu ìṣe fíìmù. Nínú ọ̀rọ̀ ẹ̀rí àwọn àgbà òṣèré wọ̀nyí, a rí bí ohun tí a mọ̀ sí iṣẹ́ fiimu Yorùbá báyìí ṣe jẹyọ láti ará eré orí ìtàgé ti àwọn Alárìnjó. Lára ohun tí ó jẹyọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀rí yìí jemọ́ ìlú Òṣogbo. Bí ó tilè jẹ́ wípé ìlú Èkó àti ìlú Ìbàdàn ṣe pàtàkì tí wọ́n sì lórúkọ gidi ní ti iṣẹ́ fíìmù Yorùbá, a ri wípé a kò leè sọ ìtàn náà ní kíkún láì mẹ́nuba ìlú Òṣogbo nítorí àwọn ẹgbẹ́ òṣèré tí ó ṣe gbòógì tí wọ́n bẹ̀rẹ̀ níbè. Síwájú si, nínú àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọ̀nyí, a rí ìbáṣepọ̀ tí ó wà lááárín àwọn ògá àti ọmọ ẹgbẹ́ àwọn ẹgbẹ́ òṣèré àkọ́kọ́ gbogbo. Àwọn ìmò tí ó jẹyọ nínú iṣẹ́ ìwádìí ìtàn yí gbogbo sì wúlò fún oríṣiríṣi èka ẹ̀kọ́. Fún àpẹẹrẹ, pàtàkì àwọn ilé tí wọ́n ń kó nǹkan ọnà àti ti ìṣẹ̀ǹbáyé pamọ́ sí jẹyọ nínú ọ̀rọ̀ ẹri Olóyè Lérè Pàímọ́. Wọ́n wípé àwọn ọfà tí àwọn lò nínú fíìmù Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́ jẹ́ ti Bàba Bàbá àwọne tí ó jẹ́ jagunjagun. Wọ́n ní àwọn ti yọ̀nda àwọn ọfà náà fún wọn ní ilé tí wọ́n ń kó nǹkan ona ọnà àti ti ìṣẹ̀ǹbáyé pamọ́ sí ní Fásitì Ìbàdàn nítorí ó túbọ̀ bu iyì kún àṣà Yorùbá.

Ó tọ́ kí a kí àwọn adarí iṣẹ́ Ògbóǹtarìgì kúuṣẹ́ ní ti akitiyan wọn lórí gbígba ọ̀rọ̀ ẹ̀rí àwọn oǹkọ̀wé Yorùbá sílè. Nítorí irú Iṣẹ́ tí ìwé kíkọ jẹ́, púpò nínú àwọn oǹkọ̀wé ni kìí sábà jẹ ẹni tí wọ́n ń fi ọ̀rọ̀ wá lénu wò. Fún àpẹẹrẹ, ọ̀rọ̀ tó dáńgájíá kan tàbí méjì—bíi irú èyí tí Karin Barber ṣe ní ọdún 1997—ló wà lórí olóògbé Olóyè Ọládẹ̀jọ Ọ̀kẹ́dìjí kí ó tó di wípé Olusegun Soetan ṣe òmíràn, tí ó sì gbé e jáde ní ọdún 2020. Fún ti Ògbóǹtarìgì, Olóògbé Láwuyì Ògúnníran ni wọ́n fi bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí ìtàn tiwọn. Kò pé tí wọ́n parí Iṣẹ́ yìí tí Bàbá náà dágbére fáyé. Lára irú Iṣẹ́ ti Olóògbé Láwuyì Ògúnníran ṣe nípa ti èdè Yorùbá jẹyọ nínú apá kejì iṣẹ́ ìwádìí ìtàn yìí. Nínú ìtàn àti ọ̀rọ̀ ẹ̀rí tí Olóyè Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ gbé kalẹ̀, a rí irú ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin àwọn àti Olóògbé Láwuyì Ògúnníran tí ó jẹ́ olóòtú ìwé ìròyìn tí wọ́n gbé kalẹ̀. Irú ọ̀rọ̀ ẹ̀rí tí Ògbóǹtarìgì gbà kalẹ̀ lénu Olóyè Túbọ̀sún Ọládàpọ̀ ṣe pàtàkì nítorí irú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ipò tí wọ́n dìmú ní ti èdè àti àṣà Yorùbá—lára rẹ̀ jẹmọ́ Iṣẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bii oǹkọ̀wé, akéwì, agbéṣé-orin-jáde, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú apá kejì náà ni a ti rí ọ̀rọ̀ ẹri Olóyè Bánjọ Akinlabì àti ti Ọ̀jọ̀gbọ́n Àrìnpé Adéjùmọ̀. Ọ̀rọ̀ ẹ̀rí àwọn méjèèjì yìí ṣe pàtàkì ní ti ìtọ́kasí tí ó ṣe fún irú ìlọsíwájú tí ó ti dé bá ìwé kíkọ, ní èdè Yorùbá, láti orí àwọn oǹkọ̀wé Yorùbá àkókò. Ọ̀rọ̀ ẹrí wọn sì fi irú ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrin àwọn oǹkọ̀wé àkókò wọ̀nyí àti àwọn tí ó ti tẹ̀lẹ̀ wọn hàn. Nínú ọ̀rọ̀ ẹ̀rí Adéjùmọ̀, a gbọ́ nípa bí nǹkan ṣe lọ sí nígbà kan rí tí wọ́n fi Yorùbá nìkan kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́

ní ilé ìwé. A sì gbọ́ nípa irú àwọn ìpèníjà tí ó ń débá èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá kíkọ́ ní àwọn Fásitì. Bákan náà, a rí nínú ọ̀rọ̀ ẹ̀rí Akinlabí irú àwọn ìpèníjà tí ó ń débá oǹkọ̀wé àti ìdí tí àwọn oǹkọ̀wé míràn fi í pa ìwé kíkọ tì.

Lápapọ̀, àwọn Iṣẹ́ méjèèjì yìí ṣe pàtàkì ní ti àfojúsùn wọn nípa ìdásí àti àgbàjọ ìtàn; wọn kò gbà ọ̀rọ̀ ẹ̀rí sílẹ̀ fún ìgbádùn tàbí fún ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò lásán nìkan. Àwọn ọ̀nà tí wọ́n sì gbà láti gbé àwọn àbájáde ìwádìí wọn àti ọ̀rọ̀ ẹ̀rí tí wọ́n ń gbà síta jẹ́ èyí tí ó rọrùn láti lò. Àwọn òpó ìtọ́ka wà ní orí pẹpẹ ayélujára wọn, wọ́n sì tún kó àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọ̀nyí sí orí YouTube. Àwọn ìwé àlẹ̀móde àti ohun èlò àfojúrí tí Digital Nollywood ti gbà jọ ṣeé wò ní orí pẹpẹ Omeka tí wọ́n ń lò. Àwọn ọ̀nà ìgbésẹ́jáde wọ̀nyí fi àyè sílẹ̀ fún gbígba ìrànlọ́wọ́ àti ọ̀rọ̀ ìdáhùn wọlé. Bí ó ti lẹ̀ jẹ́ wípé wọn kò gé kúrò nínú ìmọ̀ jíjinlẹ̀ tí ó ti inú wọn jáde, àtúnṣe fún ọjọ́ iwájú tí ó jẹ mọ́ ariwo àgbègbè tàbí ti àìṣedédé ohùn jẹyọ nínú àwọn ọ̀rọ̀ ẹri bíi mélòó kan. Ni àkópọ̀, àwọn Iṣẹ́ méjèèjì, ní àgbékalè wọn, ṣeé múlò fún ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá—àti àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ tí ó fara pé ẹ—yálà ní ilé ẹ̀kọ́ tàbí ní ti ìmọ̀ ara ẹni.